# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO ŞE WI LEJO'

VOL XIV NO 924 LAGOS SATURDAY JUNE 6— JUNE 12 1964 KOBO MEJI (2D)

IJOBA NI KO TI SI OWO

# Ara Olowogbowo E Ku Orire Kereni D'tan

EKO—Irohin ta si wa leti wipe Ijoba Apapo ilẹ Nijiria ti o ngbero lati şe kereni keji si Eko lati Ebute Apongbon lọ si Apapa ko yi ti ri owo ti nwọn mi fi şe eto gbogbo fun kereni na.

Ko yi ti si owo ti Ijọba yio san fun awọn onile Ko yi ti si owo ti Ijọba yio san fun awọn onile, ko yi ti si owo kereni, paapa ko yi ti si ibiti Ijọba yio ri owo oşişẹ.

Bi Ijọba ba gba lati fi kun owo awọn oşişẹ ti nwọn da işẹ silẹ, boya ni owo yio şiku silẹ fun awọn işẹ nla nbirlba ti Ijọba Apapo fẹ şe jakejado ilẹ Nijiria, paapa owo fun kereni keji ni Eko.

AGOGORO EYO

## Awon Eyo Ati Olojo Nfa Furaku



EKO Ọjọ oni ni ọjọ kẹfa oşu May 1964 jẹ ọjọ pataki ni ilu Eko, nitoripe ni ọjọ yi ni Oloye Ọlọla G.B.A Coker, ọkan ninu awọn Adajọ Agba ni Kotu ilu Eko yi fi ẹyọ Adamu Oriṣa sin oku baba rẹ. Baba Adajọ yi ni asiko igbesi aiye rẹ jẹ Olori awọn Ẹyọ Adimu, Ẹyọ Adimu yi ẹwẹ si ni Olori gbogbo awọn Ẹyọ ti o njade ni ilu Eko;

## Oloye Akintola San'wo Irin Ese Alhaji Adegbenro

IBADAN—Irohin kan wa ni irolẹ ana lati ọdọ akọwe onirohin wa wipe Oloye Şamuel Ladoke Akintola tise olotu Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun ti san ẹgbẹtala pọnun o le sile mẹwa pẹlu kọbọ kan (£2,260. 10s 1d) owo irin ẹsẹ ti nwọn fi igba kan paşẹ wipe ki o san fun Alhaji Dauda S. Adegbenro, baba ẹgbẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) si kotu ninu ọsẹ yi.

Nwọn ko dede sọ ọrọ na sita fun araiye gbọ bi ko şe pe ẹjọ bawo ni nwọn yio ti san gbese na ti agbẹjẹro Alhaji Adegbero, oloye Toye Coker wa pe Oloye Akintola si kotu ganran ni Ibadan.

Nigbati nwọn ni ki nwọn ma ẹnu kan ọrọ ẹjọ na ni ẹnikan nibi işẹ awọn alamojuto eto idajọ ni Ipinlẹ Iwọ orun [illegible] sọ fun Adajọ-agba, Ọgbẹni Morgan wipe Oloye Akintola ti san gbogbo owo [illegible] ẹsẹ na si kotu laiku ọpiani Oloye Coke Agbẹjẹro Alhaji Adegbenro ni awọn na ti gbọ bẹẹ, nitorina awọn ko se ẹjọ na mọ.

## Tisa To 'Pa Enmo Ejo Ku Lojiji

MAKUDI—Agbako ori ede ni oluko agba kan ọgbẹ ni Apebo ti o nkọ awọn ọmọ lẹkọ ni ilewe kan ti nwọn npe ni Sudan Mission ko lọjọ ti o pa ejo nla kan oniko de lori igi kan.

Awọn ọmọ ilewe rẹ ti o sin in lọ şe ọdẹ lọjọ na ni ki oluko yi to kuro nile ni o ti nse alaa wipe ton ni lati wa ejo ti ko jẹki awọn ara ilu sinmi na kan o n a si paa, o t o gẹẹ.

Awọn kan ni gbogbo adiẹ ati awọn a g u n tan awọn ara abule ti nwọn npe ni Mbaakon ni agọ(wo iyoku lojn ewe kejọ)

# Gomina Ipinle Iwo Orun Ba Igbimo Alakoso Agbegbe Ilu Ikorodu Soro

IKORODU—Ọlọ'la ọdẹlẹyẹ F d hausi Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun, ni ọjọ kejidinlogbọn oṣu o o k o j a nnu ipade kan ti o ṣe pẹlu igbimọ akoso agbegbe Ilu Ikorodu sọfun wọn ṣ pe ki awọn mu gidigidi lati ṣe iṣẹ ti a yan wọn fun tokantokan ati pẹlu o t i t ọ lati le ṣe iranlowo fun Ijọba Ipinlẹ ni'tori eto wọn ki apo ijọba le wa ni deede.

Ọrọ yi ni Ọlọla Fadahunsi sọ ninu esi rẹ si iwe ikini ku abọ kan ti awọn Igbimọ nipa abojuto ati ilọsiwaju agbegbe ilu Ikorodu fi lee ọwọ.

Gomina ọlọla Fadhunsi tun sọfun wọn pe isẹkisẹ ti enia ba ṣe ati iru ayekaye ti enia na wa pẹlu, kosi eyi ti ko ni ere tirẹ, nitori idi eyi o kusi ọwọ wọn lati jíforamọ ati lati lete lana ijọba Ipinlẹ eyiti iṣẹ rẹ jẹ lati mu a wa al fi wọn enia gbogbo k kiri ipinle i l u ti awọn wa labẹ Ipinlẹ Iwọ orun.

Ṣ w aju ọlọla Fadahunsi sọfun wọn pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun ti pese Ẹgbarun poun ọna marun silẹ laipẹ yi lati fi fa ẹrọ omi w a s i n u ilu nia o si seleri f u n w ọ n pe laisiyemeji awọn ara ilu Ikorodu yio ni ipin alou ira awọn anfani bawonyi ni o eyiti ijọba Ipinlẹ nsagbara lati pese silẹ.

Ṣaju tirẹ ọrọ iwe ikiniku ati ti awọn fifun Gomina Ọdẹyẹ, awọn a r a iwe Ikorodu ọ lati pese ẹrọ omi fun ilu wọn lati da ile iṣẹ silẹ ati lati fun wọn ni ojojumọ Dokita kan n i ile t os n w ọ n. Ọlọla Fadahunsi dahun wipe o yi sa bara on lati fi oju inu wo a w ọ n ibere wọnyi.

Ọpọlọpọ awọn obirin ọlọja, ọmọ ile-iwe ati awọn enia p a t a k i ni nwọn to si ọna l'ọtun ati l'osi ti awọn si ndamuso fun u bi o ti nkoja bọ wa sinu ile nnu awọn ti nwọn si kọ ku abọ ti ọgbẹni T. O. S Benson wa, ẹniti nṣe Alakoso ni irohin fun ijọba apapọ.

---

# Opo Enia Towo Lo Ri Oku Olubadan

IBADAN — Enia ti awọn ju ẹgbaa mẹdọgbọn lati orisirisi ilu ti mbẹ ni ile Ijọba Adase Naijiria ni nwọn towọ kọja lati ri oku Ọba Olubadan, Ọba Aisiki Babalọla Akinyele nibiti owọn te e si lati fun ni ẹwọ ikẹhin ni Gbọngan Mapo ni ilu Ibadan bi nwọn si ti se tẹ oku rẹ na je agbayanu ati akoko ninu itan lati igbati nwọn ti nsinku awọn Ọba ni ilu Ibadan.

Yatọ si awọn enia ti nwọn pejọ sinu gbọngan Mapo nibiti oku rẹ wa, ọpọ enia ni ni wọn tun pejọ si ode ati agbegbe Mapo bi igba igbonwon aaye ti nwọn ko ni anfani lati ri oku rẹ.

Okebadan, Ile-Ẹkọ giga ni ilu Ibadan, Ẹgbẹ Ilọsiwaju ni Ibadan, awọn Olukọ ti nkọ ni Ile Ẹkọ giga ni Ibadan. Awọn ẹgbẹ Sikaotu Ẹgbẹ Mafarọsere ati orisirisi–, si awọn ile Onisẹwo pẹlu.

Nwọn tẹ oku Olubadan na si ori ibusun kan ti nwọn ti se se l'oṣọ daradara, nwọn wọ o ni aṣọ Lamaski t'o funfun bi egbin owu, awọn ododo Oloren didun si wa yika rẹ lati fi gbe e niyi. Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun fi ododo Oloruka kan sẹyẹ fun. Ninu awọn ile-ẹkọ giga mitan ati awọn enia p a t a k i ti ododo Oloruka' kan sẹyẹ fun oku Olubadan, awọn nwọnyi tun je ẹniti nwọn tun se ẹyẹ bakanna fun awọn bi Oloye S.L. Akintọla, Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, Igbakeji rẹ, Oloye Fani Kayọde, Ẹgbẹ

L'ara awọn enia pataki ti to kọja lati ri oku Ọba na ni Ọgbẹni E.J. Philan ti ọmọ ile-iwe kanna ri pẹlu Ologbe Ọba Olubadan Oloye Otun Ibadan, Oloye Kebiowu Balogun ilu Ibadan, Oloye Salawu Aminu Ọgbẹni E.O.A Morgan ti nse adajọ Ipinlẹ Iwọ-Orun ati iyawo rẹ (ibatan Ologbe Ọba), Oloye H.O Davies, Oloye E.A. Adeyẹmọ awọn awọn Asoju ijọ ile Aladura ti Apostoliki ni ilu Naijiria ati Gana, awọn asoju Ijọba, awọn akọwe jankanjasan, awọn alufa sọsi, awọn Obinrin Ọlọja ati awọn ọmọ ile-iwe.

---

Aworan yi loni ti Ọba C.D. Akran ẹniti nṣe Alakoso eto iṣuawo Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, Ogunna gbongbo ati aṣiwaju pataki ninu Ẹgbẹ Demọ ti o ni Ijọba nikawọ ni Ibadan

Laipẹ yi ni irohin kan jade si igboro agbaiye wipe ede ko-yede kan bẹ silẹ laarin Oloye Akintọla olotu Ipinlẹ Iwọ orun ati Igbakeji rẹ Oloye Fani Kayọde ori ijimi o ṣ u m fa ti nwọn sọpe oloye Akintola fẹ lo ti o si yan ọba Akran gẹgẹbi adele on.

Irohin na jẹ irọ patapata ati isọkusọ nitoripe ko si nkan to jọ bẹẹ rara nwọn si ti kilọ fun awọn oniwe irohin lati maa sọra gidigidi fun titẹ iru irohin aiṣododo bayi.



Ọba C. D. Akran si jẹ ọkan pataki ninu awọn Minista alakikanju ni Ipinlẹ Iwọ orun ti nse iṣẹ taratara pẹlu inu kan.



# Akowe Banki Kan Fi Ewon Odun Mewa Se Ifa Je

EKO—Ekun gbojikan ohun rkedun si gba gbogbo inu gbogan ati ayika ile-ejo nla kan ni Eko ni ojo Jimo ti nse ojo kokandinlogbon osu to koja yi lehin igbati adajo agba ogbeni G. B. A. Coker da ewon odun mej dinlogbon fun awon odaran metaakan ti o ji egba metalelogbon ponun (£66, 000) ninu ile ifowopamosi (Barclays Bank) ni Eko.

Awon meta na ni Ogbeni Adesina Willoughby akowe ile ifowopamosi na eni odun mokanlelogbon, Yesufu B Yekinni eni odun merinlelogbon ati okose ielo kan, Lay Mosebolatan eni odun mej dinlogbon ti nwon gbimopo yi iwe Bank pada ti awon si ji owo na.

Adajo sapeju ve Adesina ti on so si ewon odun mewa ni igi lehin egba fun ipile ole nla jija na, Yekinni ni oluteju ati eniti o gba eru ole pamo ti on na si gba odun mewa ati Mosebolatan ti o gba odun mejo gegebi ogbo gi epuro ati alailero leri.

Esun mewa ni a awon olopa fi awon sun leri ole ti nwon ja na ojo kokanlelogun osu kefa odun to koja ni nwon jale na, awon kan wa ninu won ti awon olopa si nwa kiri.

Gegebi ejo'ti nwon ro ni iwaju adajo awon olopa ni Owo ti nwon ji na je ti awon Oyinbo onisowo ti nse sugi ni Ilorin ohun ti o jeki nwon ri aye lati se ijamba na ni wipe nwon se iwe ifigbowo madaru ni oruko ile onisowo meji kan to nwon pe ni Usuman Construction Company Limited ati 'Graham and Mallin' gegebi enipe awon ile onisowo mejeji yi nigbo ran won ati gbowo' be iro ui nwon npa.

Adajo ni ki awon olopa lo gba owokowo ti awon odaran na ba fi pamo si orisirisi ile ifowopamosi, ati moto ti nwon ti gbero lati fi owo na ra, ki nwon gba gbogbo re ki nwon si ko won fun ile ifowopamosi ti Barclays ni Eko ti o ni owo.

## Baba Agbin Igbo Bo Si Pakute Olopa

IBADAN — Ojo 'Ru ti nse ojo ketadinlogbon osu to koja yi ni Ibadan ni awon olopa mu Ogbeni Onwuna Achiren eni ogoji odun wa si iwaju adajo kan fun esun wipe o nse ogbin taba ibo o ninu oko nla kan ni bokele ati wipe o gbe eve taba igbo na pamo sowo ninu ile re eyiti o to esun iwon marun.

Awon sope ni ojo kini osu ti o koja ni Achireni losi oko re lati lo sise igbo gbingbin ... ti n ... Ojo ... Ibadan ... muye gbe ... mo.

Achireni se kanje gbangba niwaju adajo chinti akowe kotu ti ka esun re ti awon olopa ka si lese sugbon adajo sun gbigbe jo na siwaju titi di ojo keta osu keje odun yi.

Nwon duro fun un

# Aseyin Titun Wo Ipebi Ni Isehin

ISEYIN—Ni ojo oso (Sunday) ti o koja ni Asehin tuntun oba Mustafa Oyebola eniti awon afobaje yan gegebi Asehin fun ilu Iseyin wo Ipebi gegebi asa ibile awon ... ba se si nwon to fi oba je.

Egbegberun awon enia, ... juli mo ti nfe ... ri awon gbaruku te ... ti ... Ifa ti awon fi ... de Ipebi ... wa ... fun ... ogun gbako ... se ... aseyin ... bi ... wipe nwo fi ...

Gbogbo awon afobaje, ijoye ati awon ara ilu ni nwon sin oba titun na lo ni orisirisi idi Imale ni bi ti awon oba ni lati juba ki nwon to joba, lehin ti nwon pada de ni oba ti tun na ba wo Ipebi lo l ti se aisun.

Lehin ti oba ti wo Ipebi tan pelu ewu aye olowo-iyebiye ti a re ni ese, gbogbo awon enia ti nwon wa nibe si ki ola wi pe 'KAABIYESI;'

Ayo ojo na po tobe to awon ede ilu na hotesi nyin ibon, awon ilu jin, keni nwon si njo pelu, gbogbo ilu Iseyin si ndun yungba.

# Eka

Oro Oloye Beyioku (loju ewe kefa)

(loju ewe kefa)

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

# Eleti-Ofe D'araba

# ELETI-OFE

(A NWI WON BO SE WI LWO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XV. NO 924 SATURDAY June 6 — June 12 1964

## ORO OLOTU

# Agbako Iku Moto

Ni aiye ti aiye ti di a ṣgbịn ewe TABA IGBO Si ẹni gbin ẹfẹ gbure loko, ti a si ama ỌTI BỌLUGI si ẹniti nmu omi ojo, iku ti wa loju awọn dẹrẹba awamoto ilu wa, ko aniani ninu rẹ yi.

Laipẹ yi ni a gbọ ti minisita alamojuto eto ọkọ ilẹ wa nsọrọ nipa awọn dẹrẹba onimoto ile wa nibi aseyẹ kan. Minisita yi ni nkan ti o nṣe ki ijamba iku moto pọ larin wa ni ọti amupara ati aibikita fun ẹmi enia pẹlu awọn nkan bẹẹbẹ.

Ni Ipinlẹ kan ninu awọn Ipinlẹ Ijọba wa, awọn ọlọpa ṣe ikede ipe awọn ti o ku iku ijamba moto nlẹ si iwọn ọnk bi adọrin-le-nirinwo enia, ki a mọ iṣe lẹnu kan ọgọnlọgọ awọn ti moto ti fọ lapa ati lẹsẹ.

Ẹjọ tani? Ẹjọ awọn ọlọpa amumọto ilu wa ti nwọn ko fi tọkantọkan ṣe iṣẹ wọn ni Ifẹ owo riba ọbigba ti gba wọn lọkan pupọ. Owo riba yi wọn lẹwu ọbẹgẹ ti o fi jẹ wipe ko si ọwọ ẹniti nwọn ko le gba a. Bi awọn ti ngba a lọwọ awọn dẹrẹba BỌLẸ-KAJA lọna oko ni nwọn ngba a lọwọ awọn baba onimoto ni arin ilu, ti nwọn ni moto lati ọdọ awọn alaṣẹ.

Awọn baba onimoto ojiji yi paapa ma nfi iwa birukutu, a nwa moto sare a sa diju ṣe awada, nwọn ko si ka ẹmi enia kun nkankan rara. O ni iwọn are ti awọn ni la i sa larin ilu gbọn ẹwọn baba onimoto wa asa are ju bẹ ẹ lọ.

A bẹ awọn ọlọpa amunmọto, ki awọn ma pe awọn onimoto yi ni oṣu mẹta lati ma kẹ wọn lọna ti nwọn ni lati gba wa moto wọn.

# Eleti-Ofe D'araba

# Iwe Si Olotu

# Wolewole Ati Awon Olonje

Kiniṣe ti awọn akọwe wolewole (Sanitary Inspectors) ko ṣe wahala mọ lati ma bẹ awọn obinrin ti o se onje ta kakiri mọ? Tabi nwọn nfẹ ki nwọn ma fun wa ni majele jẹ ni?.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa kesi awọn ọga awọn akọwe wolewole wipe awọn ọmọ iṣẹ wọn ko wo bi awọn obinrin olonjẹ mọ.

Ọrọ imọtoto ninu iṣọ awọn olonjẹ ti ilẹ ilu Eko nikan, bi ẹ ba fẹ ki ẹ lọ si Ogunpa ni Ibadan ẹ o ri wipe idọti iṣọ wọn ko ba oju mu, afi awọn wolewole ilu Abeokuta ti nwọn ko fi iṣẹ wọn ṣere rara.

Ẹ jọwọ, ẹ ba wa kesi awọn wolewole ilu Eko ki nwọn ṣe iṣẹ wọn ni aṣetan lojojumọ, ki nwọn ṣe iṣẹ nwọn ni aṣetan lojojum ki nwọn ma wo iṣọ awọn olonji kiri l'Eko Ebute Metta, Mushin, Yaba ati Ajegunlẹ. Ẹniti ko ba jẹki gbogbo nkan si o nlo mọ ki awọn ifẹ e lejọ. eleyi ni ajọ kọ awọn Olonjẹ yoku lẹgbọn.

Ladipo St, Mushin — Emi ni, Lasisi Akanji

## A Fe Iwe Itan Eko

Olotu, Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati bere lọwọ awọn ọkawe pin boya a le ri ẹniti o mọ ibiti nwọn ngbe ata iwe itan Eko ti nwọn sode lati iwọn nkan bi ọdun mẹjidinladọta sẹhin ti a le ka ni akarọgbọn.

Emi ti rin kakiri ile awọn ọtawe l'Eko, 'ni Ibadan ati ni Abẹokuta nko ri iwe itan Eko rara. Mo gbọ wipe Oyinbo Ojiṣẹ Ọlọrun kan ni o fi igba kan kọ iwe itan Eko.

Boya a le ri ọkan ninu awọn ọkawe yin ti o mọ ẹniti o se iwe itan ilu Eko ni o sọ fun wa.

Ẹ ṣe pupọ, Olotu fun aye ti ẹ gba 'mi, iwaju ni ẹ o ma lọ.

Ijero Ebute-Metta — Emi ni, T. Adeleke

**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

62, Massey Street, (Faji Market),

LAGOS, NIGERIA.

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Oja Eja Tutu Fe Si Sile Ni Okitipupa

OKITIPUPA — Awọn ilajẹ Apẹja pẹlu awọn onişowo ẹja fẹ lati şi ile itaja kan ti iye owo rẹ ẹdẹgbẹta pọnun ni Ebute Okitipupa nibiti awọn ti nşowo tabi ti nra ẹja yio ma ra ẹja laişi ọwọ onilaada nibẹ rara.

Ninu ipade kan ti awọn ẹgbẹ apẹja ati onişowo ẹja şe ni ilu Obenla ni agbegbe Okitipupa ni awọn ti pinnu lati da ile-itaja na silẹ, nwọn si kede fun gbogbo awọn ti awọn nra ti nwọn si tun nta ẹja nile ati lode ni igberiko Okitipupa wipe ki awọn maşe ra ẹja mọ ni ẹja titun kan ti awọn şẹşẹ şi silẹ fun ẹja tita nitori laisi ọwọ onilaada nibẹ rara. Nwọn si tun sọpe awọn ko ni faramọ ki onişowo kan gba laada ti tọ lori ẹja mọ, lẹhinna nwọn si parapọ lati ba awọn Ẹgbẹ Apẹja Ibilẹ Okitipupa da owo şişe pọ.

Ẹgbẹ Apẹja Ilajẹ na si gba awọn ti nşowo ẹja niyanju lati ma a gbe ẹja wọn lọ si ile ẹja tita na ti nwọn şẹşẹ fẹ si nibiti ko ni si laada pupọ lati gba lori ẹja tita.

## Oloye Fani Kayode Sope Iro Ni Iwe-Irohin Kan Npa



Oloye Fani Kayọde.

IBADAN- Gẹgẹbi irohin kan ti o jade loju iwe irohin PILOT ni ọjọ kẹtaleogun oşu t'o kọja lọ wipe IJA NLA BESILẸ NINU IPADE ẸGBẸ DẸMỌ' Oloye Fani Kayọde, igbakeji olori Ipinle Iwọ Orun sọ wipe aişododo si otitọ ọrọ ati isọkusọ ni o jẹ, ati wipe iru ọrọ bayi a ma şi enia lọna.

Oloye Fani Kayọde sọ wipe ọrọ aişododo si ju ati enia ti iru ọrọ b ilẹ, eyiti o buruju lati gbọ ati wipe iwa alaiọgbọn ni fun enikẹni ti o jẹ ọmọ Yoruba lati ma sọ ọrọ abuku kakiri lati fi tu ọmọ Yoruba ka.

Suwaju si i Oloye Fani Kayọde tun fi nyeni wipe ọpọlọpọ awọn ti nwọn korira ẹgbẹ Dẹmọ ngbero pọ pe ki ẹgbẹ Dẹmọ bajẹ şugbọn yatọ si ero wọn Ẹgbẹ Dẹmọ ndagba soke ni.

Iru awọn akrira ati aba nijẹ ti nsọnọ ẹgbẹ Dẹmọ la d ra bayi nfi han gbangba lati pupọ fun 'gbogbo agbaiye nipa ipade ẹ a ti egbe Dẹmọ şe, nitoripe wọn ko ni anfani lati de ibi ipade na gẹgẹbi otẹlẹmuyẹn.

Oloye Fani Kayode pari ọrọ re pẹlu ikilọ si iru enia ti o tẹ irohin buluje ti o tẹ jade si gbogbo aiye lati cẹkun iru irohin alaişododo bẹ ẹ.

## Ara San Pa Obinrin Aboyun Kan

OSHOGBO-Ni ilu oshogbo lẹnu igọlọ yi ni irohin kan wa wipe ojo nla kan rọ ninu eyiti ara nla kan san ti o si pa iyawo ile kan, lẹhinna o si mu ki Wuudiya kan yarọ bamubamu.

Ẹnikan ti nkan yi şoju rẹ sọ fun wa wipe inigbati o di ojumọ ti Alice Akintọla obinrin aboyun na agbalẹ ile fişẹ-onjẹ ti o nse ta ni agọ awọn oşişẹ agbẹ ti ijọba igberiko oke ọsun ni ilu Oshgbo ni ara na san lojiji, lọgan obinrin na ba şubu lulẹ, o si ku patapata.

Bi iya nla ba gbeni şanlẹ ni ọrọ na da, ara kanna ti o san ni o tun şe ijamba fun Wundiọla kan ti oruko rẹ njẹ Foyekẹ Akinọla ti o jẹ ọmọ bibi inu obinrin aboyun na, o si mu ki ẹsẹ rẹ mejeji rọ bi ewe o şubu lulẹ o daku gbọnin.

# Okunriu Kan Ya Ore Lapa Nidi Oti

CALABAR—Ẹmu oguro lọ da ijọngbọn silẹ nibiti nwọn ti nşe ajọyọ oku kan to ku ni ileto Ikot ni agbegbe Kalaba laipẹ yi ti o fi mu ki ọkunrin kan Paul padanu ọwọ osi rẹ patapata, Adajọ si sọ Akpan Ibanza ti nwọn ni o gee lapa na sẹwọn ọdun mẹta.

Ninu ẹjọ ti nwọn ge lapa ro, o sọ fun adajọ wipe ni ọjọ kẹtadinlogun oşu to kọja lọ ni o ati ọrẹ on kan lọsi ibi ajọyọ isinku oloye kan, Ekpo Ededi ti ileto Apabuyo, nigbati on fẹ fin taba simu laimọtẹlẹ agolo taba na bọ sinu akeregbe ẹmu ti ọkan ninu ibatan siogbe na bu fun awọn alejo rẹ

Paul nigbati on fẹ yọ agolo taba na kuro ninu oguro, ni ọdaran na ba tako on wipe on ti ru ofin işẹdalẹ awọn si sọ oguro fifun di nkan miran kiki ika bọ inu rẹ ti on tika bọ ọ.

Nigbati ariyanjiyan de Paul ni on fẹsẹ fẹ sugbọn Ibanga gbaa le lọna ile o si bẹrẹsi şa on ni ada lapa ati ni gbogbo ara, ẹni Paul ni on figbe ta fun irora ada na.

Niwaju adajọ, Ibanga ọdaran na se kanlẹ pe on ko jẹbi rara nitoripe ẹşẹ ni o jẹ fun ẹnikẹni lati ti ika rẹ bọ inu ẹmu ni ilu awọn.

### We oju ewe kefa fun awon Danadana ti o da Oyinbo Lona.



# Awon Olopa Mba Onisegun To Sowo Rojo

[illegible]KO — Afurasi [illegible] Ogbeni Adahunse kan ti oruko re ... Adegbuji pelu ekeji re kan ti ko nise lowo ... Osuagba ni awon olopa ti won sun esun owo ... ti awon gbimo pelu Yiyi iwe pada ati ole jija ... ti sun ojo igbejo won si ojo keji osu kefa odun yi.

[illegible] ti awon olopa ... wipe [illegible] won ni, awon ... ni awon ore meji na lu iwa banki ... ni ojo kinni osu kefa odun yi ni adugbo ti awon ... ni Nelson Street ni Yaba nigbati nwon lo be ... Ukaiga ore won kan ... agbofi wo nibi ti o ngbe.

Leiyin ti o ti se won lalejo ... awon ti gbadun ara won, ... awon si ajomitoro oro lowo owo, Onisegun na ati ore re ... fun Ukaga wipe awon

le je takada owo poun meru ... ti won ni ... Najiria ni ... yi fun un awon wa so fun Ukaga pe ki o mu egba poun wa ... awon so di egbe ... poun fun un.

Ukaga tun se alaye fun adajo kotu wipe lehin ti on ti fun awon ... ni poun ... ti on ko ... won ... adasan ... won ko ... Awon olopa ni nwon ba on ... won ... awon ... o.

---

# Awon Danadana Da Oyinbo Kan Lona Lona Ibini

OWO — Awon danadana mefa kan, ... won l'oju won ti nwon da Oyinbo kan lona Ogbeni Williams Meddison Sandisson ti nse ... (Fagh Timber) ... ibi ... owo ... ipa ... gba ... poun ... lowo re ni a gbo wipe awon olopa ni ilu Owo ... won kiri lowo lowo.

Gegebi irohin ti a gbo Ogbeni Williams ti awon danadana na ... lati ... do re Melege ni agbegbe Benin lati lo gba owo ti o fe fi san owo osu fun awon osise re.

Ngbati o ... moto bi o ti de ... kedogun larin ... ilu Owo ... ati Ifon, awon danadana ba yo ... lati buba won ... nwon si fi ... moto Oyinbo na.

Awon meji ninu awon danadana na ni nwon ... Ogbeni Williams mu awon merin to ku si ... moto re lati gbe owo t'o lo gba.

Bi nwon ti gbe owo na tan ni gbogbo won bere gbo, nwon tun fo ese moto akeru kan eyiti iba ... se ranlowo ati olugbala fun on.

## Moto Pa Olopa Kan

Isele ... kan sele ni irole ojo ... ti ... Lokan ... ni opopo Denton Bridge Street ni Ebute-Metta nigbati moto kan kolu olopa kan ti o si ku ...

Gegebi ohun ti ... iku ojiji ... a gbo wipe olopa na fe lati ... ti ... ni pe moto ... kan ... wipe moto ... ti ko ... login ...

... awon ... lo ... Eko ... moto gbe olopa ... oruko ... ti o nlo ... si ile ... awon lakilaki.

---

## Oloye Beyioku Ni Awon Egbe Alaruko Ni Nwon Ko Ba Awolowo

EKO — Oloye A. O. Fagbenro-Beyioku ... ninu egbe Demo tuntun (NNDP) ... oro ... awon omobinrin ti awon sese ... ni ... Ex... wipe yi Oloye ... awon ... egbe Alaruko (NCNC) ni nwon ... ni ... fe ni Awolowo ti adajo ju se won ... Ijoba Apapo ... Oloye Akintola rara.

Oloye Fagbenro-Beyioku ni isosokuso ni awon kan ti nwon nso ejo kakiri wipe Oloye Akintola ni o ko wahala ba Awolowo nibiti o gbe wa.

Fun bi wakati kan ni o fi nse alaye ... ti awon se da egbe tuntun na sile. Oloye Fagbenro ni awon si ti se tan lati fun awon ogiri ... lowo ... ise won.

Oloye Fagbenro ni ... awon Yoruba ti iya ti nje ... gba ... ti nwon ... awon se da egbe Demo sile.

---

## Elewon To Salo Bosi Owo Olopa Ninu Ile-Oti

ONITSHA — O ... ninu ... ti ... ile oti kan nibiti nwon ... ni ilu Onitsha

ninu ose ti o koja nigbati ogbologbo janduku elewon kan sare dide lojiji kuro larin awon onifaaji ore re na laidagbere fun won, ti o si mbe lo bi igala sinu igbo lati lura fun won ti nwon nwa a.

Nkan ti o fa oro na ni ni wipe nigbati awon olopa wo inu ile-oti na lojiji isansa elewon na ba fura si won o si gberaso bi ogan, awon olopa papa si se ifura si on na nwon so o nwon ba a gba tele e wo o lo laifaagun lo titi, owo won si te e.

Gegebi nkan ti awon olopa so ni wipe oruko elewon na n je Alcazor, eniti o ti sa kuro ninu ogba ewon lori ewon edun medogun ti o nse lowo fun esun olosa ati folefole.

Alcazor ni oruko elewon ti o salo na nje nwon ni lati inu osu kewa odun t'o koja ni awon Woda ti nwo ... nigbati o salo nibiti awon ... ewon ... ise.

---


E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI-OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.

# BBC Discuss Education In Africa

The development of education in African countries, and some of the problems to avoid, were discussed by Ibrahim Tah r of N geria in a BBC African Service broadcast.

"In Africa today," he said, we are fashioning our own systems of education. I am not suggesting that what we have so far seen of the development of education in Africa is unsatisfactory. Nevertheless, a tendency might develop simply to adopt the traditions of education in the more advanced countries of the w-rld."

Referring to a book called ANTHROPOLOGY AND EDUCATION," Tahi said that the essays n it highlighted some of pitfalls of the systems tha he hought Africans should avoid.

One essay said that in a society that had to certain extend already achieved most of its mean and objectives the educational system tended to emphasise technique at the expense of exploration and discovery. "In a society like that; said Tahir, "the author points out that individuals are likely to be swallowed up by the pre-occupation with the techniques and complicated details, lose their ability to think clearly and lost respect for learning completely. And that is to say the least, dangerous for any society."

The individual and society was the subject of another essay reviewed in the BBC broadcast. The individual's choice and assumption of a popular role in society would obviously be affected by his education, which would in turn, depend on the educational system. This means; said Tahir, that it is not only the role of the individual that is affected by the educational system, but also the role of the individual's society in the universal family of societies.

The authour of another essay considered that a new approach to language was needed' He contend's said Tahir, that language is evolutionary. Certain languages lend themselves far more than others to growth and adaption, and therefore have a better chance of becoming a universal medium of communication. For individuals societies with a language of their own, certain problems arise when it cames to new aspecs of leaning, such as technology in an African society. This says the author, emphasises a need for a new approch. the evolutionary approch to liagu∎st cs.

## BBC Programme

Durin the coming week the programmes in the BBC African Service, after the NEWS at l cal time on on 17. 81 and 21. 61 megacycles, in the 16. and 13 meire bands, will be as follows.

| | |
|---|---|
| Sunday, June 7 | London Fanfare |
| Monday, June 8 | A Book For Today, Focus On Africa, In Perspective, For You At Home, |
| Teausday, June 9 | A Book For Today, Postmark Africa, Africa, Africa Mirror, Calling Ghana. |
| Wednesday, June 10 | A Book For Today, Focus On Africa, African Star Feature: York University. |
| Thursday, June 11 | A Book For Today, The World As We See It, Calling Nigeria. |
| Friday, June 12 | A Book For Today, Focus On Africa, World Horizens, Writers' Club. |
| Saturday, June 13 | Showtime, For Parents And Teachers, Calling Sierra Leone. |

**For World-wide and Local news read ELETI-OFE your newspaper.**

CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28; Balogun Street, Lagos.

AGOGORO ẸYỌ

## Awon Eyo Ati Olojo Nfa Furaku

(O bẹrẹ loju ewe Kinni)

Awọn Ẹyọ nwọnyi ni: Ẹyọ Age e, Ọlọgẹdẹ B jutaiye, On fia pupa, Oloku Ẹyọ Kesọkọ, Ayọ Onisẹmọ, Ẹyọ Ouitẹlọ, Ẹyọ Oni tọiọ, Ẹyọ Oshodi, Ẹyọ Ormọlẹ.

Ọjọ alaiye ti daiye tabi ni igba Atijọ awọn Ọba tabi Oloye ilu Ek ni ma nfi Ẹyọ sin oku wọn, ṣugbọn aiye na ti pada ni ode oni; awọn Samari, Olowo tabi enia pataki ni ilu a ma fi Ẹyọ Adamu Orisha ṣe Ayẹyẹ oku baba wọn,

## Tisa, To Pa Enmo Ejo Ku Lesekese

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

gbe Ti o ni ejo na ti pajẹ tan, nwọn ni ko si ọdẹ ti o gboya lati paa.

Lọjọ ti oluko yi nlọ pa abami na ibon oloju meji rẹ ni o gbe lọwọ o si ki ni ẹkunrẹrẹ. Bi o ti de in igbo ti nwọn ni ejo na ni ma nwọ wa ni o tẹju kan 'ri lo i igi ti o ngbe sun lọwọ.

Warawere tisa yi ti yin ibọn rẹ si i, ibọn na bọ lọwọ rẹ o a si bẹrẹsi gbọn titi o ṣubu lulẹ, o si ku bamubamu.




Our tradition is based on principles of lasting validity: Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the products performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.



MERCEDES-BENZ

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

## ARO EYO

Emi Ajigiaai aria ginni
Emi aria ginni-ginni wọja,
Emi afiaju wọja ti aria geerere,
Ọbun wọja pa ṣuẹṣuọ,
Ni iṣẹra afiaju wẹle,
Ni mẹṣi ikọle nimọdẹ isaiye.
Emi ayanpọntan bi ọni yande,
Emi ewọn balẹ ro wọyọwọyọ
Emi lọmọ Onipọnpọju agbeṣẹyẹ
Ti nṣọ-ọ Saadatu ni mẹṣi ikọle
nimọdẹ iraye.
Emi awọruru, Afiruru,
Emi awọruru jana bi ere,
Emi apa ọmọ abeloko sinku
Ti nf ṣọ iyi rẹ wẹlẹ ni imẹsi ikọle nimọdẹ iraye,
Igi n a ṣegbo bonranin-boranin
O t n ṣegbo barayi-baraiyi,
Owo eni laa bu fabuke,
Oko laba ẹkun we faraṣoko
Otun ni abosi, ni imẹsi ikọle
nimọdẹ iraye.
Emi Aboju paa, aboju pọo
Emi aboju kọ mọna yeriyeri,
Lesi ma kẹkun lọna jaṣawo,
Igbin woo, oju ẹlẹbọ,
Adamu Oriṣa, Ọmọ ajoku ṣamuṣamu,
Otun ni abosi ni imẹsi ikọle nimọdẹ iraye
Njọ akala ku, atawo atọgbẹri.
Nwọn sinku akala.
Awo lo kọkọ sin tiwọn,
Kila o fi sinku akala
Awọn Agbada funfun balayi
Lao fi sinku akala,
Aropalẹ funfun bọnlọnjọ, lao fi sinku akala,
Opambata ati akẹtẹ meji l'ao fi sinku akala,
Ijẹ ti Awo baku, aropalẹ we ma fa felefele lojude Ọba, nimẹsi ikọle nimọdẹ iraye.

HU HA HA HA!

WE SURUKURU

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ola Onatade 15, Kosoko Street, Lagos, P O 467, Lagos.